OWE

Eyi ko to ofo, eyi ko to ofo fila Imale nku pempe.

# Irohin Yoruba

VOL IX No 459 MONDAY APRIL 26, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

# Ijoba Mba Olota S'ejo

ABẸOKUTA--Ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni awọn Ọlọpa wa mu Ọba Ọlọta Timothy Oloye Ọlagoroye Keji timọle pẹlu awọn enia marun, Hezekiah Dare, Yesufu Alakanṣe, Yesufu Akinde, Yesufu Idowu ati Ọladunjoye Diyaolu.

Ẹṣẹ ti awọn Ọlọpa ka si wọn lọrun ni wipe nwọn lo jibiti owo-ori fun awọn Ẹgbẹ Aiyepeju Ọtta pe ti ẹnikọkan nwọn ba ti le da ṣile mẹwa-mẹwa wa ti awọn ba si ti fun Ọba Alake Abẹokuta ni ọgọrun pọnun nibẹ, nwọn ko tun ni san owo-ori kankan mọ.



ỌBA ỌLỌTA
Ti Ijọba mba a ṣe ejọ nisisiyi.

Awọn Ẹgbẹ na si da owo na, gbogbo apapọ owo ti nwọn da na si jẹ ẹgbẹrinla pọnun (£2,800) ti nwọn sọ pe awọn gbe fun Ọba Ọlọta ati awọn ti nwọn mu timọle pẹlu rẹ bi arufin.

Nwọn ti ko awọn arufin na wa si iwaju Adajọ Kotu Kekere Abẹokuta, ṣugbọn nwọn koiti bẹrẹ si ro ẹjọ ti Adajọ na fi yẹ gbigbọ-ẹjọ wọn na si ọjọ kọkanla oṣu ti mbọ. Oloye I. A. Shodipọ, ọkan ninu Igbimọ Ẹgba ni o duro fun Ọlọta, bẹni nwọn si gba iduro awọn yoku pẹlu.

Ki Ọlọpa to lọ mu Ọba Ọlọta na gẹgẹ bi arufin ni Ọgbẹni I. F. W. Schofield Ajẹlẹ Agba Abẹokuta ti fi iwe ran Ajẹlẹ Kekere si Ọba Ọlọta pe Ijọba ṣi da a duro gẹgẹ bi Ọba na, fun igba diẹ, nitorina o ni lati yọ ọwọ rẹ kuro ninu aye iṣelu ati ninu Igbimọ aṣofin ilu titi ti nwọn o fi fi ori ẹjọ ti Ijọba mba a ro ti si oju kan.

Nwọn bi Ọba na ni ọjọ kẹfa oṣu kọkanla ọdun 1906, o di ẹni ọdun mejidinladọta lọdunni, ile-iwe St. James School Ọtta ni o gbe kọ ẹkọ, on ni ẹnitu o kọkọ ṣe akọwe (bailiff) ni Kotu Ibilẹ Ọtta ki o to bẹrẹ si fi mọto akero ṣe owo, eyiti o nṣe titi o fi jẹ Ọba ni ọjọ kẹwa oṣu karun ọdun 1949, ọmọ marun ni o ni.

## Kwame Sa Aburo Re Pa

ASANKRANGWA G.C.-A gbọ pe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu kini ọdun yi ni ariwo ta s'okẹ lala wipe okunrin kan lati "Bremang" ni agbegbe Asankrangwa ti orukọ rẹ njẹ Kwame sa aburo rẹ ni ada pa!

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ ọkunrin na ni pe, lati nkan bi ọsẹ meji ni are igbona (were) ti kọlu ọkunrin yi ti o nsọrọ kantan-kantan, ni nwọn ba fi mu u lọ si ile Oniṣẹgun fun itọju, nigbati oju rẹ walẹ ni nwọn ba mu u wale.

Nigbati o di ni owurọ ọjọ yi ni ọkunrin yi ba bẹrẹ si pọn ada, nibiti o ti npọn ada yi lọwọ ni o ti pe aburo rẹ yi ran niṣẹ. Bi aburo rẹ na ti pẹhinda lati lọ jẹ iṣẹ ti ẹgbọn rẹ ran an ni ọkunrin yi ba ṣa a ni ada ni ipakọ, njẹ ki aburo bojuwo ẹhin o tun ṣa ni ada niwaju, nibẹ ni o ti lulẹ ọkunrin na si bẹrẹ si ṣa a titi o fi ṣa a ni asa pa.

Gbogbo ilu rọ kẹkẹ ni nwọn ba gba ada lọwọ ọkunrin yi, ni nwọn ba fi de ni okun lọwọ ati lẹsẹ. Ki nwọn to gbe ọkunrin ti nwọn sa lọgbẹ yi de ile-iwosan (Hospital) ni Samreaboi, emi rẹ ti kọja.

A gbọ pe ọkunrin ọdaran na wa ninu itimọle lọdọ awọn Ijọba, ṣugbọn a koiti mọ bi nwọn yio ti ṣe ẹjọ rẹ si. Lọwọ agbako iku ojiji Oluwa rere gba wa.

## Hadji Ayinla Je Balogun Ilu

EKO-Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni ẹsẹ awọn enia pataki pataki pe si Mọṣalaṣi Jimọ Ilu ni Victoria Street lati fi Hadji Amodu Ayinla Alli-Balogun jẹ oye Balogun ilu Eko ropo ẹgbọn rẹ, Hadji Busari Balogun ti o jalaisi ni nkan ọdun kẹta s'ẹhin.

Bi awọn ero ti pe si Mọṣalaṣi bẹ na ni nwọn pe si ilẹ baba Hadji Amọdu Ayinla na ni 35 Victoria Street ti nwọn nyọ, awọn ẹbi rẹ ati awọn ọrẹ rẹ si ba a lọ si Mọṣalasi na nibiti Lemọmu Ilu, Abudu Karimu Nollah gbe we lawani Oye Balogun fun un.

Wo oju ewe kẹrin

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

## Eniti O Ti Je Mayor Eko Ku

EKO-Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Ọgbẹni Emmanuel Augustus Oluyẹle Bright ẹniti o jẹ oye Mayor Eko gbẹhin ku si ile-iwosan Ijọba "Creek Hospital" ni nkan bi agogo meje koja iṣẹju mẹdogun alẹ nigbati o di ẹni ọdun merinlelogọta l'aiye lẹhin ti o ti ṣe aisan fun igba diẹ.

Nwọn ṣe isin isinku rẹ ni Ile-Isin Ijọ St. Paul's Breadfruit Church" ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kejilelogun osu kanna, lati ibẹ ni nwọn gbe ti gbe oku rẹ lọ sin si ilẹ-isinku Ikoyi Atijọ. Awọn enia pataki pataki ni o pe si ibi isinku na, ero pọ bi omi lọjọ na.

Ologbe na kọ ẹkọ ni ile-iwe C. M. S. Grammar School Eko, gbara ti o jade ni ile-iwe o ṣe iṣẹ olukọni (teacher) fun igba diẹ ki o to lọ ṣe iṣẹ akọwe labẹ awọn Reluwe nibiti o gbe siṣẹ t'ara t'ara ati otitọ tobẹ gẹẹ ti o fi di pe awọn ọga rẹ gbe e si ipo ọga iṣẹ (Office Assistance), ki o to fi gba aye isimi [Pension] ni nkan ọdun kẹje s'ẹhin.

Gomina Nigeria Ọlọla Arthur Richards [Lord Milverton] fun un ni iwe-OWỌ (Certificate of Honour) nitoripe o ni pe ologbe na se iṣẹ rere fun igbesia mu rẹ. Ologbe na jẹ ọkan ninu awọn Olufọkansin pataki ninu Ijọ St. Paul's Breadfruit Church. Ọpọl pọ awọn iwe ẹkọ keekeẹ ni o ṣe nigba aiye rẹ, awọn iwe bi "The Currency Question" ati "The Prohibition of Alcohol in Nigeria".

Ni ọjọ kejidelogun oṣu kẹwa ọdun 1952 ni nwọn yan an si ipo Mayor Eko dipo Dokita Ibiyinka Ọlọrun-Nimbẹ ti o ti pari ọdun kan tirẹ.

Wo oju ewe kẹrin



Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Aṣiwaju awọn Alakoso Ijọba Iwọ-Orun pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ nibi oku Ọlọla Akeredolu-Ale, Ọgbẹni Awolọwọ duro lẹba Iboji Ologbe na o nsọrọ iwuri nipa iwa ati iṣesi Ologbe na nigba aiye rẹ.

